# IDAJỌ IKẸYIN ATI IGBALA KURO NI EGIPTI

## Ẹksodu 11:1-10; 12:1-51

## ẸKỌ 56 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Nigbati emi ba ri ẹ̀jẹ na, emi o ré nyin kọja" (Ẹksodu 12:13).**

**Iṣẹgun Dé**

Akoko Ọlọrun lati mu awọn eniyan Rẹ̀ jade kuro ni oko-ẹru pẹlu iṣẹgun ti de wayii! O ti fi agbara nla Rẹ̀ hàn lọna ti ẹnikẹni ni ilẹ naa kò fi le wi pe oun kò i gbọ́ nipa Ọlọrun rí. Ogunlọgọ awọn ọlọrun ti awọn ara Egipti n sin ko le ràn wọ́n lọwọ nigba ipọnju wọn. Anfaani ki ni ó jẹ́ lati maa sin awọn ọlọrun ti kò le ṣe ohunkohun fun ọ?

Bawo ni Ọlọrun ti Bibeli ti yatọ to! Oun ti ṣeleri pe irun ori wa kan ki yoo ṣegbe. Eyi fi hàn pe o n kiyesi ohun ti o tilẹ kere. O ti wi pe "Nitoriti oju OLUWA nlọ siwa sẹhin ni gbogbo aiye, lati fi agbara fun awọn ẹni ọlọkàn pipe si ọdọ rẹ̀" (2 Kronika 16:9). Bi a ba wà lati maa wu Ọlọrun Oun yoo ṣe itọju wa daradara.

Ninu ẹkọ yii Ọlọrun wi pe Oun yoo ṣe itọju awọn eniyan Oun to bẹẹ gẹẹ ti awọn aja ki yoo fi le ya ẹnu si wọn tabi si agbo-ẹran wọn paapaa. Ṣugbọn ki ni yoo ṣẹlẹ si awọn ara Egipti? Ikú yoo bẹ gbogbo ile wò. Akọbi jẹ ohun ti o ṣe iyebiye ju lọ laaarin ẹbi, lori wọn ni idajọ yii yoo sọkalẹ si. Ro o wò bi idile kọọkan yoo ti maa ṣọ̀fọ̀ nigba ti ayanfẹ ọmọ wọn ba ku lojiji! Ibanujẹ naa yoo pọ ju pe ki gbogbo ilu kú, nitori nigba naa ko ni kù eniyan kan lati ṣọfọ.

**Ohun Irọpo**

Bi awọn Ju tilẹ jẹ ayanfẹ, wọn kò wà lailẹṣẹ, bi akọbi awọn ara Egipti ba si n kú nitori ẹṣẹ wọn, akọbi awọn Ju i ba ti kú pẹlu, bi ko ba ṣe nitori ẹ̀jẹ ti o wà lara ibugbe wọn. Idile kọọkan ni lati pa ọdọ-agutan kan ki o si fi ẹjẹ rẹ sara ilẹkun ati sara òpó ile, ẹ̀jẹ naa yoo si ṣe ami fun angẹli apanirun naa pe ọdọ-agutan naa ti kú ni ile naa dipo akọbi, angẹli naa yoo si ré kọja lọ.

**Ajọ Irekọja**

Ohun ti o ṣẹlẹ ni Egipti ni alẹ ọjọ yii ṣe pataki fun gbogbo eniyan lati ayebaye. O ṣe danindanin to bẹẹ ti Ọlọrun fi wi fun awọn Ọmọ Israẹli pe wọn ni lati bẹrẹ eto titun fun oṣu kikà, ki wọn si fi eyi ṣe oṣu kin-in-ni. Lati igba yii lọ wọn o maa gbe igbesi-aye titun. Wọn ki yoo tun ṣe ẹru mọ bi kò ṣe ọmọ Ọlọrun ti a sọ di ominira. Ohun ti wọn ṣe lalẹ ọjọ yii -- jijẹ ọdọ-agutan irekọja -- wọn ni lati maa ṣe e lọdọọdun "laelae", ki wọn má baa gbagbe idande nla ti a fi mu wọn jade kuro ni Egipti.

Nisisiyii a o ri ohun ti o ṣẹlẹ. Ọlọrun fun awọn eniyan naa ni aṣẹ pataki ti wọn ni lati tẹle kinnikinni. Ni ọjọ kẹwaa oṣu wọn o mu akọ ọdọ-agutan kan ninu agbo wọn. O ni lati jẹ eyi ti o pé, nitori bẹẹ wọn ni lati yaa sọtọ titi di ọjọ kẹrinla oṣu naa boya ki wọn ba le yẹ̀ ẹ́ wò daradara, ki o ma ba jẹ eyi ti o ni abuku kan. Ni alẹ ọjọ kẹrinla ni wọn ni lati pa a ki a si wọ́n ẹjẹ rẹ̀ sara opo ile ati atẹrigba ẹnu-ọna –ki i ṣe sori ilẹ nibi ti a ti le tẹ̀ ẹ mọlẹ. Lẹyin naa wọn ni lati sun ọdọ-agutan naa ki wọn si fi ewebẹ kikoro jẹ ẹ. Eyi ni a n pe ni ọdọ-agutan irekọja, a si pe ase naa ni Ase Irekọja, awọn Ju olufọkasin si n pa a mọ́ ni ọdọọdun. Titi di oni ni awọn Ju n pa ilana yii mọ́ ṣugbọn wọn mu ti ẹ̀jẹ kuro.

**Ọdọ-Agutan Irekọja Wa**

A ti sọ pe ase yii ṣe pataki fun gbogbo aye, ki i ṣe fun awọn Ju nikan. Ọlọrun ti ṣeleri fun Abrahamu, Isaaki ati Jakọbu pe nipasẹ iru-ọmọ wọn ni a o ti bukun fun gbogbo orilẹ-ede aye, eyi ti o tọka si Kristi. Ọdọ-agutan irekọja yii jẹ apẹẹrẹ Kristi. Ninu 1 Kọrinti 5:7 a kà pe: "Nitori a ti fi irekọja wa, ani Kristi, rubọ fun wa." Ofin Ọlọrun wi pe laisi itajẹsilẹ ko si imukuro ẹ̀ṣẹ (Heberu 9:22); nigba ti Jesu si di Ọdọ-Agutan Irekọja wa ti Oun si ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ fun ẹ̀ṣẹ wa, ko ṣanfaani mọ lati maa pa ọdọ-agutan lọdọọdun ni akoko Ajọ Irekọja. Fun wa Jesu jẹ "ọdọ-agutan ti kò li abuku, ti kò si li abawọn" (1 Peteru 1:19). Jesu ta Ẹjẹ Rẹ̀ silẹ O si kú ki eniyan ni aye ba le là ki o má si kú nitori ẹ̀ṣẹ rẹ̀.

**A Lo Ẹ̀jẹ Naa**

Ni ti pe awọn Ọmọ Israẹli gbọran si Mose ti wọn si pa ọdọ-agutan naa, kò gba wọn lọwọ ikú. Ani igbagbọ́ wọn ninu Mose kọ́ lo dá wọn si. Wọn ni lati fi ẹjẹ naa sori atẹrigba ẹnu-ọna ati sara òpó ile ki angẹli apanirun to le ré wọn kọja. Bẹẹ gẹgẹ ni iku Kristi lori agbelebu, Ẹjẹ Rẹ̀ ti a ta silẹ, ani igbagbọ́ wa paapaa ninu Rẹ̀, kò ni le gba wa lọwọ iku ayeraye. Ohun kan wa ti a ni lati ṣe – a ni lati jẹ ki Oun fi Ẹjẹ Rẹ̀ naa wẹ ọkàn wa.

A le ṣe eyi nipa titọ Jesu wá pẹlu ọkàn ironupiwada ki a kaanu fun ẹ̀ṣẹ wa ki a si pinnu lati kọ̀ wọn silẹ; lẹyin naa ki a gbadura titi a o fi mọ̀ pe Oun ti dariji wa. Lọna bayii ni a fi tun wa bi -- bibẹrẹ igbesi-aye titun, kuro ninu ide Satani. Ikú tọ́ si wa fun ẹ̀ṣẹ wa, Ọlọrun si beere bẹẹ pe: "Nitori ikú li ère ẹ̀ṣẹ" (Romu 6:23). Ṣugbọn Jesu ṣaanu fun wa; ati nitori O kú fun wa, awa ki yoo kú mọ́ ninu ẹ̀ṣẹ wa bi a ba jẹ ki Ẹjẹ Rẹ̀ bo ọkàn wa.

A **Kò Ṣẹ́ Egungun Rẹ̀**

Lẹyin ti wọn ba ti sun ọdọ-agutan naa tán, wọn ni lati fi ewebẹ kikoro jẹ ẹ. Bi o ba ṣẹku rara wọn ni lati dana sun un ki o má ba bajẹ. Ranti pe ọdọ-agutan naa jẹ apẹẹrẹ Kristi, Onisaamu si wi pe, "Nitori iwọ ki yio fi ọkàn mi silẹ ni ipò-okú, bẽni iwọ ki yio jẹ ki Ẹni Mimọ́ rẹ ki o ri idibajẹ" (Orin Dafidi 16:10). A kò gbọdọ ṣẹ́ egungun ọdọ-agutan naa: a si ri i pe a mu aṣẹ yii naa ṣẹ pẹlu. Nigba ti a fi Jesu kọ́ sori igi agbelebu, ti awọn ọmọ-ogun si

wá lati ṣé egungun itan gbogbo awọn ti a kàn mọ́ agbelebu, wọn ṣẹ́ egungun itan awọn arufin ti a fi kọgi lẹgbẹ Jesu; ṣugbọn nigba ti wọn ri i pe O ti kú wọn fi I silẹ lọ. Dafidi ti sọtẹlẹ pe, "O pa gbogbo egungun rẹ̀ mọ́ kò si ọkan ti o ṣẹ́ ninu wọn" (Orin Dafidi 34:20). Bayii ni Oun tun mu apẹẹrẹ ọdọ-agutan naa ṣẹ.

Awọn eniyan naa ni lati wọ aṣọ, ati bata, pẹlu ọpa wọn lọwọ wọn, ki gbogbo wọn si mura silẹ lati rin irin-ajo, bi wọn ti n jẹun. Boya aṣẹ yii rú wọn loju nitori Mose ti sọ fun wọn pe ki wọn má ṣe jade kuro ni ile wọn ni alẹ ọjọ yii titi angẹli apanirun yoo fi rekọja; taa ni yoo ha si gbero ati bẹrẹ irin ajo ni ọganjọ oru?

**Ọfa Ikú**

Ṣugbọn ni ọganjọ oru igbe ta. Idaamu nla ṣubu lu Egipti. Ni olukuluku ile – lati ori itẹ titi lọ de ibujẹ-ẹran – ni akọbi kú. Wo bi ṣiṣọfọ ti pọ to lori awọn ayanfẹ wọn ti o ṣalai si! Mose ko ṣẹṣẹ tun ni i sọ fun Farao mọ́ pe ki o jẹ́ ki awọn eniyan naa lọ. Ni oru ọjọ naa gan an ni Farao pe Mose ati Aaroni, o si wi fun pe ki wọ́n kó gbogbo awọn ọmọ ati gbogbo agbo-ẹran ati ọ̀wọ́-ẹran wọn lọ, ki wọ́n ṣe ohunkohun ti wọ́n bá fẹ́, kiki pé kí wọ́n sá à lọ! Gbogbo awọn ara Egipti sare lọ si ile awọn ọmọ Heberu, wọ́n si wí fun wọn pé ki wọn yara tètè fi ilu silẹ. Wọ́n fun wọn ninu wura ati fadaka ati ohun ọ̀ṣọ́ wọn – eyi sá à jẹ́ èrè diẹ fun isinru wọn. Ọrọ̀ wọn kò jamọ nnkan kan niwaju ikú.

**Ijadelọ Kánkán**

Awọn Ọmọ Israẹli kò duro pẹ́. Ohun gbogbo ti wọ́n le gbé ni wọ́n mú lọwọ, wọn si bẹrẹ si lọ. Wọn kò fi iwukara sinu iyẹfun pipò wọn, ṣugbọn wọ́n gbé e gẹgẹ bi ó ti wà, wọ́n si fi ilẹ Egipti silẹ. Ọgbọ̀n ọ̀kẹ́ (600,000) eniyan, lai ka obinrin ati awọn ọmọde ni ó rìn lọ si aginju ni oru naa. Ninu awọn àdàlù eniyan Egipti ti wọ́n ti rí iṣẹ́-iyanu ti Mose ṣe bá wọn jade pẹlu. Bawo ni iran naa ti dùn tó lati wò ni ọjọ naa! Awọn kan rò pé awọn ẹgbẹ́ naa ju aadoje ọ̀kẹ́ (3,000,000) lọ niye, lai ka gbogbo ọwọ-ẹran ati agbo-ẹran wọn. Rò ó wò bi igbe awọn ẹran-ọsin yoo ti maa dún ti ekuru yoo si maa fẹ́ soke bi wọn ti n fẹsẹ rìn jade kuro ninu oko-ẹrú wọn!

A mú awọn ileri Ọlọrun fun awọn eniyan ayanfẹ Rẹ̀ ṣẹ. Wọn kò gbọdọ gbagbẹ idande nla yii laelae, ṣugbọn lọdọọdun wọn ni lati maa ṣe Ajọ Irekọja gẹgẹ bi iranti. Wọn ni lati maa sọ fun awọn ọmọ wọn nipa iṣẹlẹ nla yii, ki wọn si mú wọn mọ ire ati aanu nla Ọlọrun yii. O ṣe danindanin pe ki awọn obi maa kọ́ awọn ọmọ wọn nipa ifẹ Ọlọrun , ati ojuṣe wọn si I.

Awọn Ọmọ Israẹli ti wà ni irin-ajo nisisiyii si ilẹ ileri naa. Ṣugbọn irin-ajo naa ṣẹṣẹ bẹrẹ ni.

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni arun ikẹyin? Taa ni ó si pa lara?
2. Bawo ni awọn Ọmọ Israẹli ṣe bọ́ kuro ninu arun naa?
3. Apẹẹrẹ taa ni ọdọ-agutan naa i ṣe? Sọ ọna gbogbo ti Jesu fi mú apẹẹrẹ yii ṣẹ.
4. Nibo ni a fi ẹjẹ naa sí? Nitori ki ni?
5. Bawo ni a ṣe lè gbà wá là?